# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. III. No. 135. SATURDAY, FEB. 14, 1925. FOURPENCE.

**Declared Circulation 1,300 Copies Weekly.**

## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

"**Specialities:** Enamelware, Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails, Rangoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, padlocks, Beads, etc., etc., etc."

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

OYINBO **J. F. SICK**

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, origiriisi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita :—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Wajì, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Olokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ Didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumãdan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa ; A ni nkan wọnyi fun tita :—

Ikoko Taba Onigi, Jigi, Aṣọ Aran, Ẹrọ Agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn Onjẹ Ipanu, Aṣọ Iṣ'ọṣọ, Ẹrọ Ere Ọmọde, Ohun Ọṣọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maṣini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati Irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile Owo ni:— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

# LEVER STORES LTD.

## THE PEOPLE'S STORE

NOTHING NEW UNDER THE SUN

BUT ALWAYS

# Something New

AT

# LEVER STORE

AND

# Nothing over 1s.

*Editor & Proprietor:*—
ADEOYE DENIGA,
*Offices:* 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

"ẸNYIN ONINURE,
Ẹ FI WA SI'LẸ LỌ,
A O SỌKUN NYIN TITI
JESU PA SỌKUN RI."

Gbígbọ̀n rìrì la gbọ̀n ni aṣalẹ *Sunday* to kọja nigbati a gbọ ti ajalu iku Ọgbẹni Oninure ni Dada Adeṣigbin ọga ninu awọn onişowo ẹrọ aranṣọ eyiti o jalu ilu ni iwọn agogo mọkanla-abọ ãrọ *Sunday* na ni'le rẹ, "*Abayomi Villa*" 4, Layẹni *Street*. A ko mọ pe o ti fẹ diẹ si ọgagun yi, airi ti a ko ri tobẹ ni'le mu ni ro pe jagun ti gbe'ra lọ si idalẹ lati lọ bẹ orişirişi Ẹka Ṣọşi rẹ wò (ẹyini ni Ṣọşi *Bethel* ti Ọmọ Ibilẹ) gẹgẹ bi işẹ rẹ nigbagbogbo.

Enia nşàn bi omi ni ãrọ *Monday* ti a sin i lọ si ile rẹ pipẹ, lẹhin igbati a ti gbe lọ si Ṣọşi *Bethel* nibiti awọn Alufa Agba J. S. Williams, J. S. Lakẹru ati Alufa Olubi şe etutu ikẹhin si oku na lara lọna ti Onigbagbọ.

Nşe ni ẹkun npe ẹkun ranşẹ, fun ọ̀fọ̀ nlanla yi ti o kan ilu.

A ba Ọgbẹni Akintunde Adeşigbin Ọgbẹni Oke Adeşigbin, Ọgbẹni J. Layẹni ati awọn ọmọ oku, ati iyekan rẹ gbogbo ati awọn ẹbi t'o ku kẹdun ọ̀fọ̀ nla yi.

"Bi o ti kú, o nfọhun sibẹ."

ORI KANA TU'RUGBỌN YẸU-YẸU!

Ẹrin kekere kọ ni a busi ni ọsẹ to kọja nigbati ọrẹ wa kan sọ pe nitori ki awọn ti nwọn wa yọ ọti ra ni Ṣabu on maşe fi ara han fun awọn enia ri, ni o şe ma nję ki on ma tan ina elepo Oyinbo dipo ina atupa oïji (*Electric Light*) ti on fa sile, ti on si gba si Ṣabu na pẹlu; ohun ti o mu wa bere lọwọ ọrẹ onişowo ọti wa yi ni pe nigbakugba ti a ba nkọja gba Ṣabu rẹ lalẹ a ko nri ki o ma tanna ti o gbà na. Nigbati a si bere idi rẹ lo fi fun wa ni irufẹ esi bayi; a ti şebi o nşe arọ̀ró iye titan atupa na loşoşu ni, şugbọn esi to fun wa na tẹ wa lọrun gidigidi.

Ẹnyin Ọ̀rí kánà tu'rugbọ̀n yẹu-yẹu, ẹ ma ro pe eyi jẹ itiju fun nyin. Ẹ ko ha ti şe jẹ ki oloku ma ru oku rẹ lọ, nipa fifi igo ọti na silẹ? Tabi orin yi ni ko fun nyin ni aye rẹ̀ ndan?

B'o lo mu mọ, a si ma dun,
Ọti, ọti, a si ma dun!!!

ETI ỌBA NI'LE, ETI ỌBA LOKO.

A gbọ pe ọga işẹ kan to nşişẹ Ọba ninu "Ọbasunmigbe" ti Ijọba şẹşẹ ntẹdo nisinsinyi ni Yaba, gba owo ẹhin bi nkan şile mẹwa-mẹwa tabi marun-marun lọwọ awọn enia ti nwọn nşişẹ labẹ rẹ laipẹ yi, şugbọn a woye pe owo ti o gba na ti di ọ̀ri ti o nyọ mọ lọwọ; nitoriti ọga işẹ na ti di ẹni à-lé-mu Ọba nisinsinyi.

ẸNYIN WỌBIA, WỌMBILIKI,
WỌMUWỌMU!
Ẹ F'ẸSỌ LA'BẸ GBIGBONA!!!

Kilọkilọ la şe fun awọn a-wa mọto ko ero ti nwọn mu mọto nwọn lọ si Ikoyi ni *Monday* ọsẹ yi nigbati ilu nsin Ọgbẹni wa Dada Adeşigbin Ologbe lọ si ibi isinmi rẹ ikẹhin; ẹnu ko ha ya ẹnikẹni lati gbọ pe şile kọkan fun ẹnikọkan ni awọn olojukokoro baba ole yi bu fun awọn enia ti nwọn ba fẹ wọ mọto wọn na wa si ile pada lati Ikoyi, lẹhin igbati a ti sinku tan.

A mọ diẹ ninu awọn enia l'ọkọnrin l'obinrin ti nwọn diju san owo yi pẹlu

**White's Golden Male Tonic.**
(DOUBLE-STRENGTH)

Whenever a women has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs. Now while it is true that many women suffer from disease yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. *White's Golden Male Tonic* (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs

**Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.**

*The Reliable Dispensary, 41 Offin Road, Lagos.*

N.B. NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.

**SHAKE THE BOTTLE.**

AREMO FUN OKUNRIN

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Are, Ęda ati gbogbo Arun ti ki ję ki ọkunrin ṣe abiamọ.

N.B.—O ye ki gbogbo ọkunrin ma lo igo mejimeji lọṣoṣu—Ișe ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price ten shillings ( 10/- ) per bottle.

ṢABU J. A. SULE—OLOGBE

A fę ki awọn ọrę ati onibara Ologbe J. A. Sule ti Eko ati ni Idalę mọ wipe a ṣi Ṣabu rę fun ọja tita, a si din owo ọja na si pọ ọ.

Irin ișę kafinta, ti alagbędę ati nkan bi agadangodo, apoti, posi ati ohun ọṣọ oniruru ohun ti a ko l daruko tan: ya wa wo tirę ki wọn to ra tan ma ję ki ọbọlę ki ọ.

A BOON TO BUSINESS MEN.

Type-Writers of different Brands e.g. Barlock, Monarch, etc. in good condition, on sale.

Prices reasonable to the man in the street.

Terms :—Cash.

Apply to the Editor.

## CONGRATULATIONS

TO

DR. A. ADEDEJI ISHOLA, D.M., D.Psc.

*The First Known African Graduate in Divine Metaphysics.*

We heartily congratulate Dr. A. Adedeji Ishola, D.M., D.Psc., &c &c. for his latest literary achievements in qualifying for the two degrees of Doctor of Metaphysics, and Doctor of Psychology, in the College of Divine Metaphysics.

The College is a recognised one in America, as well as in England where it is ably represented by so high and distinguished a personage as Mr. G. Hooper, F.R.A.S., F.T.S., &c. &c. of "Cranemoor" fame,—Student of the Sciences, Philosophies and Comparative Religions.

This College of Divine Metaphysics is a first class one: it has its own State Charter, and its Diploma is equal to any University First Course Diploma.

The Courses in this College are studied all over the world by University Graduates, Professors, Physicians, Attorneys, Bishops, Clergymen, Musicians, etc., etc.,—in fact they are studied by men in all the walks of life.

We are creditably informed that Dr. Adedeji Ishola is the very first African on the West Coast to graduate in a College of Divine Metaphysics and that he is now busy preparing to qualify for the Highest Degree conferable by this College,—viz: Doctor of Divinity or D.D. We wish Dr. Ishola further success in his preferment.

We also congratulate all the Members of The Brotherhood Congregation, Isholarian Temple for the brilliant literary attainments of The Founder of this very promising and ever progressing Organisation.

Later on, we hope to give the reading public further information about the Prospectus, etc., etc., of the College of Divine Metaphysics in America.

*Eko Akete* Wireless.

WO'BI ENIKEJI,

Oniruru Posi li o wa fun tita; lọdọ Paul I. Samuel owo wọn bęrę lati Pọun meji abọ titi de Pọun mejila șile mejila. Ę le ri wọn ra ni 40, Campbell Street, leti Ile-isin Ṣọși Ebenezer; ati ni No. 71, Igboșere Road, nitosi *King's College*.

# Memorabilia.

## DADA ADEŞIGBIN.

Merchant: dropped his foreign name "Moses" in after years; educated in St. Paul's (Breadfruit) School, Lagos, started life as Master Tailor; with the Motto "Business before Pleasure" came into prominence by his famous Singer Sewing Machine business; presented a donation of 120 guineas to his Church Bethel on attaining the age of 45, 1910; has published Annual Almanacks of African life (illustrated); lost his eldest son ..yo in Sierra Leone (whither he had gone for further training) during the Influenza Epidemic 1918, visited Europe and America in company with Mr. E. A. T. A. Johnson of this country who played the part of "Private Secretary" to him, 1905.

Joined the great majority on Sunday 8th February, 1925. Aged 60 years—From *Nigerian Who's Who.*

## FACTS AND FIGURES.

### Sir Harry Johnston On An All-Black Republic.

**MARCUS GARVEY'S IDEA SUPPORTED BY THE GREATEST EUROPEAN AUTHORITY ON AFRICA.**

The following extracts appeared in the *Afro-American* (10/1/25):—

"*Looks for a big Race Republic in Africa*:—London England, January 7, (By A. N. P.)—In an interview here recently, Sir Harry Johnston, the empire builder, who carved out Rhodesia, Uganda and Nyasa for Great Britain during his forty years in Africa, told a correspondent for the *Chicago Daily News* that he visioned a vast republic of the colored races playing its part in the balance of world power. In the coming clash of color which he envisions, white control in Africa will be imperiled and the heart of the dark continent will again belong to its own.

"I don't expect to see a black Africa in my time," said Sir Harry, who is 66. "However, it is entirely possible that within half a century all of Africa from the Zambesi to the Great Sahara may be one great black republic.

*Points To Liberia As Example*:—"Many considerations go to indicate the eventual success of a black domain throughout Africa. The deadly climate in the central portions—the Congo and the Cameroons—a climate absolutely fatal to whites, is one factor. The encouraging success of Liberia in being able to maintain its identity is another. The rising desire for independence—the following tide of color—is yet another."

"Many of the Negro and Negroid tribes in Africa are fully capable of independence and unless their political instincts are depraved by the ingress of whites they should be able to take care of themselves. The African type at its best is a fine type of manhood."

Sir Harry is usually considered the greatest living authority on Africa. He went out to the Congo in 1880, worked with Stanley. His scientific discoveries and researches have made him even more signally known. For two decades he collected fauna, flora, geology and made an especial study of its language. He is the author of the only avilable work in English on the Bantu tongues."

After all said and done Marcus Garvey's dream of an African Republic is not as fantastic as some people have been trying to make it. It is not impossible of realisation. At present it appeared very dark to many but it may materialise some day. The fact that no less an authority on Africa than Harry Johnston Esq. (a European) could envision the same idea is an evidence that it is nothing that should cause us alarm if we are not indifferent to facts. But alas, some critics—are they fanatics?—have shouted themselves hoarse this side of the water, raising alarm over the idea of a Black Republic. Do there critics believe that the Negro is as GOOD A MAN as the European? We trow not.

ADEKANBI.

## IN MEMORIAM

In loving and affectionate memory of our dearly beloved Father,

REVD. JOHN ADOLPHUS OLUYIMIKA BRIGHT

Who departed this life at Rahama Station, Bauchi Line, Northern Province, on the 12th day of February, 1905.

"We all shall live for ever
In realms so pure and bright
Oh aid us, then, our Father
To think and act aright
To cheer the broken hearted
To aid the suffering one,
And through life's various changes
To say "Thy will be done"

May he rest in peace *Amen*.

Thomas Augustus Olusoji Bright
Joanna Olujonwo Bright
John Adolphus Olatunde Bright
Nusiratu Ayinke Bright
Albert Eoward Oludolapo Bright
Charles Augustus Birtwistle Olufunmilayo Bright
Robert Herms Oluyele Bright
Felicia Frances Unastella Ashabi Bright
Etc., Etc., Etc.

**Mr. H. Campos's No. 4 Shop.**

Goods in endless variety are on sale at H. Campos's No. 4 Shop, 173, Tokunbọ Street, Ararọmi Market.

*Cash on delivery.*

## EKO AKETE

EKO, SATURDAY, FEB. 14, 1925.

### ẸNITI KO NI ITIJU, OJU KAN NI BA NI, A RI ROGODO, A TO T'ẸṢIN.

Lati ọjọ ti Alaiye ti d'aiye ni a kî fẹ alãnu kù lata awa ọmọ Anọbi Adamọ: bi o tilẹjẹpe enia buburu pọ, o ju'gbẹ, enia rere wọn ju oju lọ.

O si ni iye awọn ti nwọn nmọ riri ore ti ẹlomiran ba ṣe fun wọn, yálà nipa iṣẹ ni o, tabi nipa ohun miran gbogbo; eyiti o si fẹrẹ dabi ẹni wọpọ larin wa ni igboro ilẹ yi ni pe ki a duro fun enia nibi iṣẹ, eyini ni ni ọdọ awọn Oyinbo onişowo.

Ni igba lailai ni irufẹ awọn ti a nduro fun lọna bayi mọ iyi, ti nwọn si mọ ẹyẹ nipa titọju iṣẹ wọn, ati nipa fifi ẹmi imõre han awọn ti o ṣanu fun wọn bayi, ti nwọn fi nle ri okele ẹnjẹ bu s'ẹnu gẹgẹ bi ede wa.

Diduro fun ni pe orisi meji tabi mẹta ekini, a le duro fun enia kọ iṣẹ bi iṣẹ gbẹ́nàgbẹ́nà tabi alagbẹdẹ l'ọgba Ọba (*Indentured Apprentices in Carpentary or Blacksmithery in Government Departments P.W.D. or Nigerian Railway*) ekeji, a le duro fun ẹniti Ọlọpa sọ́gọ fun ẹṣẹ kekeke tabi eyiti o gbọwọ; ẹkẹta a le duro fun ẹniti o fẹ ma ṣe akọwe onişowo ibaṣẹ lọdọ Enia Dudu tabi Oyinbo.

Anu ṣeni lati so ti iwa a-b'ara-more-jẹ ati iwa a-do-nkia (*I don't care*) ti awọn ẹlomiran nhu ni igba isinsinyi tobẹ ti pupọ ninu awọn ti a nduro fun na fi nfi iwa wọn sọ pe ki awọn olõre wọn wa gba idi lá.

Ẹ jẹ ki a sọ nipa iduro ẹkẹta :—

Ko ha ni iye awọn ti a ti sọ di onigbese àpàpà-ndodo ninu awọn enia wa ti nwọn ṣanu ẹlẹgbẹ wọn lọna ti a ti la silẹ yi, eyiti o mu ẹlomiran ninu wọn ri ohun ti ko jẹ ni igbọnsẹ nigbati o ba fa ẹniti o duro fun na bi ẹni fa òtò-npòrò lati ri bi õkan tabi ẽji gba lọwọ rẹ fun onigbese rẹ, ti o ti fi owo olowo ati ọja ọlọja ṣ'ejure fun Sẹliya Akankẹ tabi Beatrice, nigba ti iyẹn ti ra dẹdẹ ti o si ti gba dẹdẹ ti o fi atike pa oju bi ẽgun Kurumọ ti o si fi jòjò oni jòjò ge'di lọ sọdọ ọkọ olugbese ninu Ṣabu ti a fi si ṣugbọn ti onitọhun kò ni irù ?

Ọrẹ wa Ọgbẹni Hector Ọlatunde Glover ti 1, *Edwin Street*, ni Ita Faji ko ha mọ ohun ti oju on ri nigbati awọn oṣu meji mẹta sẹhin l'ọdun to kọja nipa ọdẹlẹsinrin kan ti o duro fun lati san gbese, ṣugbọn ti o di akoko ati sanwo, ti onitọhun fi ãke kọ'ri pe ọwọ on mẹwẹwa rẽ, nitoripe on ko ni õkan lọwọ bi Aja; ãgbárègbátọ̀ rẹ̀ kò ha niye igbati onigbese na pe Ọgbẹni na l'ẹjọ pẹlu Ọgbẹni Hector O. Glover ti Adajọ si ni ki nwọn lọ san gbese fun onigbese; ṣe gẹrẹ bi awọn Akẹran ti o ra onigbese mu ti nwọn fẹ ti ilẹkun ile ẹniti o jẹ gbese yi papa, ṣe bẹni "ma ṣe igi lõre yi" bere pe nwọn ti lọ ti ilẹkun ile Ọgbẹni Glover oniduro on na? Nitoripe ẹru pilẹ lọdọ rẹ! ẹ tilẹ jẹ ka bi Alaimõre yi bi ogún le pọ titi ka fi ha aladugbo? A fi irufẹ seria ti a le da fun irufẹ Arigid'enia bayi fun ẹnyin ọkawe wa lati so, ẹ ko ri bi gbà, ranmi si ti nwa di ẹlẹru nigbẹhingbẹhin ?

Ẹ tun gba ọkan si :—

Ni koipẹ yi ni a gbọ ti Ọgbẹni William A. Cole, alagba ti 11, Ita Agọngbọn, ti o nṣe Gbẹnagbẹna ati Akọle, ti on ati ẹnikan duro fun Mọsondoko kan ti o nṣe akọwe lọdọ awọn Oyinbo onişowo kan; nigbati o si ṣe wõ, ti onitọhun *short* gburugburu bi ẹni fa aṣọ ya ti a si pe on ati awọn oniduro rẹ l'ẹjọ, ti Adajọ si da are—gẹgẹ bi o ti yẹ ki o ṣe—fun awọn Oyinbo Onişowo na pe ki nwọn lọ gba owo wọn lọdọ akọwe yi pẹlu awọn oniduro rẹ, ẹ mọ ohun ti akọwe alakọke yi ṣe ? Ko bẹrẹ si fi ẹsẹ fẹ, ti o joye isa-nsa mà tun de, a le ko lọ ko le lọ, bi Keni (*Cain*) ? Nigbati o ma gun u nkọ, bi igbati orisa gun Filani; ko ni ki awọn oniduro on ma rãn nibẹ, on ko ni õkan lọwọ bi "T'ani'Ọlọrun"!!! èdè re o, ẹnyin enia wa; tani irufẹ iwa yi ye, ti aini ailojuti ni tabi ti aini fáyà, tabi ti abaramoreję? Irufẹ ẹni yi o wà

ti o ni iwa gbregbere yi lọwọ, t'on ati Ọlọrun meji ni ẹlẹjọ.

A ha le ka ẹniti o ṣe iru ore bayi ti ile rẹ fi di ti ohun ti a nlu wararo agogo gbanjo si ni igbẹhin-gbẹhin? Ogo ni a sọ pe a ko nri alanu bi ti igba atijọ mọ, bawo ni a o ti ṣe ri? Nigbati o ba jẹ pe bi o duro bi ẹdegbẹta pọun (£500) fun ẹnikan nibi iṣẹ, ti o jẹ pe ọna a ti le dasi ẹniti o duro fun u lọrun ni yio ma wa kità.

Awọn Ọgbẹni J. K. Coker, ati C. A. Thompson (Ainde Olobi) le gbagbe ohun ti oju nwọn ri nipa diduro fun enia? Ni gasikiya ni a ni owe pe ore ki ipa ni, wahala ni o ngbe ni si.

A ko sọ pe gbogbo awọn ti a nduro fun ni o ni irufẹ iwa jatijati bayi lọwọ, agbẹdọ! ṣugbọn ti a ba da iye awọn ti a nduro fun na si ọna mẹwa, ipa ni a o fi ri ẹni meji ti ko ni iwa bẹ lọwọ.

A tanmọ pe gbolohun ọrọ diẹ yi yio mu iyipada ātātā wa, a si fẹ ṣẹ ni ikilọ pe ki ẹniti ko ba to pẹmu iduro rù, ki o maṣe fi itiju ko arun nipa gbigbọjẹgẹ iṣẹ na.

Ẹ gbọ bi Iwe ti a ṣe ni ọdun 1921 ti a npe ni "Gbọngbọnkankosi" ti wi ni ewe kẹsan rẹ (*Page 9*).

SI ONIDURO.

Adanu nla ni eyi
Fun ẹni t'o ba gba duro
Bawo ni ikanujẹ na ti pọ to
Ka ri ohun ti ko jẹ ninu igbọnsẹ
Anu ṣe ni lati ri ẹlomiran
T'o nf'okun fun'ra rẹ lọrun
Nipa ṣiṣe onigbọwọ igbese
T'o ẹ'ẹti tun lati san;
Maṣe jẹ omugọ enia
T'o ni ẹgba ni'le
To tun lọ ya ẹgba l'ode
Ọpọlọpọ ohun ini ẹlomiran lo ti di
tita
Lati di'gbese ẹni t'a duro fun
T'a ta ti ko ni'ru,
Maṣe jẹ baba tabi iya-alanu yẹyẹ
O ṣẹ'gi ta fi koriko da'na
Ẹni ti ko ni jọjọ l'apa
Ki nda'ṣa mo ki ọ, ki ọ;
A ki nfi 'tiju k'arun
Sibẹ a mọ pe "oju lo nroju ṣanu,"
Ṣọra ki 'rufẹ anu bayi
Maṣe jẹ 'banujẹ rẹ ni'jọ miran.

---

IGBIMỌ FUN ARẸMỌ ỌBA

(*Part II.*) [*Copyright.*]

[*Lati ọwọ* ATARI-AJANAKU.]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji.

Ni ọsẹ ti o kọja, a sọ nipasẹ Arẹmọ-ọba ti o nbọ ni ilẹ yi, ati ipamọ ti ilu nṣe lati pade rẹ. A sọ bi iwe ti Dokita Randle kọ si Ọlọla Loya Shyngle ti ṣe sọ wahala Ọgbẹni B. C. Vaughan ati G. Debayọ Agbebi di ofo, ati bi Gomina ti so Igbimọ ti nwọn yan ni ile *Lieutenant Colonel* Moorhouse di oku, ti o si yan Igbimọ miran fun ara rẹ, ati iru enia ti a yan si Igbimọ na.

L'ai fi ẹnu ṣe ete l'ẹṣọ, ati Igbimọ ti awọn Dokita Randle kọkọ yan, ati eyiti nwọn tun yan ni ile *Lieutenant Colonel* Moorhouse, ati eyiti Gomina papa sọ wipe on yan, ko si eyikeyi ninu wọn ti o dara to Igbimọ ti ilu yan ninu Ipade gbogbo-gbò ti nwọn ṣe ni *Glover Memorial Hall*. Eyiti Igbimọ Gomina iba fi dara ju ti ilu lọ ni wipe, Oyinbo ko si ninu Igbimọ ti ilu yan; ninu Igbimọ ti Gomina, ẹwẹ, Oyinbo p'apọju!

Awọn ti Gomina sọ wipe on fi inu didun yan na niwọnyi:—

The Hon. the Chief Secretary to the Government. (Oyinbo.)
His Honour the Lieutenant Governor, Northern Provinces. (Oyinbo.)
His Honour the Lieutenant-Governor, Southern Provinces. (Oyinbo.)
The Hon. Deputy Chief Secretary. (Oyinbo.)
The Hon. the Treasurer. (Oyinbo.)
The Hon. the Director of Marine. (Oyinbo.)
The Hon. the Secretary for Native affairs. (Oyinbo.)
The Hon. the Senior Resident, Kano. (Oyinbo.)
The Hon. the Secretary, Northern Provinces. (Oyinbo.)
The Hon. the Secretary, Southern Provinces. (Oyinbo.)
The Hon. the General Manager, Railway. (Oyinbo.)
The Hon. the Director of Public Works. (Oyinbo.)
Lt.-Col. W. B. Greenwell, D.S.O., (Oyinbo.)
The Inspector-General of Police, Southern Provinces, (Oyinbo.)
The Resident of the Colony. (Oyinbo.)
The Principal Assistant Secretary. (Oyinbo.)
The Right Revd. Bishop of Lagos, D.D., (Oyinbo.)
The Right Revd. Bishop Terrien, D.D., (Oyinbo.)
The Revd. Oliver Griffin, (Oyinbo.)

The 3 elected Members for Lagos, (Enia Dudu.)
The Member for the Colony Division (Enia Dudu.)
The Commercial Member for Lagos, (Oyinbo.)
The Member for Shipping, (Oyinbo.)
The Chairman of the Lagos Chamber of Commerce, (Oyinbo.)
Mr. O. Alakija, representing the Lagos Town Council, (Enia Dudu)
The Manager of the Bank of British West Africa, (Oyinbo.)
The Manager of the Colonial Bank, (Oyinbo.)
Mr. Henry Carr, I.S.O., (Enia Dudu.)
Dr. John Randle, (Enia Dudu.)
Mr. Peter Thomas, (Enia Dudu.)

Iba orukọ awọn ti Gomina kọkọ fi si Iwe-ikede bi Igbimọ rẹ fun iyẹsi ti Arẹmọ-ọba ni eyi. Ṣugbọn ki a ma ri, ki a ma ri lẹhinna, oruko Loya A. Alakija ati ti Dokita Ọbasa yo ninu ọpọn ifa Gomina; lẹhin ọjọ melo si i, orukọ Ọgbẹni G. D. Agbebi ati ti Dr. R. A. Savage si yọ nibẹ pẹlu.

Apapọ gbogbo enia ti o wà ni Igbimọ Gomina yi nisisiyi jẹ:—

Oyinbo mẹrinle-logun (24.)
Enia Dudu mejila pere (12.)

Bẹni ti a ba ko gbogbo Enia Dudu ti o wa li Eko yi jọ si apakan, ki a si ko Oyinbo si apakan, Enia Dudu pọ ju Oyinbo lọ ni ilọpo ọna mẹtale-logọfa; ti a ba si wipe ni gbogbo ilu *Nigeria*, a o ri i wipe Enia Dudu pọ ju Oyinbo lọ ni ilọpo ẹdọtadin-l'ẹgbẹrun ọna.

Ki a tilẹ fi eyini silẹ, ki a wo ibi iṣẹ Ọba, ati ti awọn Oyinbo Oniṣowo; nibiti a ba ri Oyinbo kanṣoṣo pere, a o ri to adọta Enia Dudu tabi ju bẹ lọ nibẹ: ẹnikẹni ti o ba si de Ọgba awọn Oṣiṣẹ Ọba ni Apapa, ni Yaba, ni Okun, ati ni ibomiran pẹlu ri, yio ṣe akiyesi wipe Enia Dudu ti o nṣe iṣẹ pẹlu Oyinbo kanṣoṣo nibomiran ni ibi iṣẹ wọnyi lé ni igba enia.

Larin awọn oṣiṣẹ nikan kọ ni iru eyi wa, o wa larin awọn Akowe pẹlu. Kurumọ kan, ibẹ meji ni o wa kakiri gbogbo ibi iṣẹ Ọba, ati ti Oyinbo Oniṣowo pẹlu.

Nitorina, bi Gomina tilẹ yan Enia Dudu mẹrin-le-logun, ti o si yan Oyinbo mẹfa pẹlu wọn gẹgẹ bi Igbimọ ti yio ṣe iyẹsi fun Arẹmọ-ọba, ko laifi; ṣugbọn gẹgẹ bi Igbimọ na ti wa nisisiyi, o ko ejika ru, o pọ si apakan; Oyinbo si pọ pupọ nibẹ ju Enia Dudu lọ l'aimidi.

Ibaṣe wipe Oyinbo pupọ ju Enia Dudu lọ ni Arẹmọ-ọba nfẹ lati ri, họwu, kini nwọn nfi oku ṣe l'orun, awọn tani o wa ni Ilu Oyinbo bikoṣe alawọ funfun?

Ẹniti o ba nwa enia gigun lati mọ, ki o lọ si Ilu Oyinbo, ti o ba si ṣe ẹniti o kuru ju rárá lọ ni o nwa ni, nwọn kun Ilu Oyinbo to wọbu. Bi o nfẹ lati mọ ọlọgbọn julọ, tabi omugọ ti o gọ ju iṣọ, olõtọ, eké, olè, ọlọṣa ti o le ko ile ni ọsan gangan, alakinkanju, ọjẹdọlẹ, alailojuti, ati ọdaju, alanu ati ọsọnu, panṣaga-panṣakuta, oninurere, ika, olowo, abọsi ọmọ oju Gọta (*Gutter*) apania, ani, ti o ba nfẹ lati mọ oniruru ati oniwaiwa enia, ekute-bu-nijẹ-fẹni, lọ si Ilu Oyinbo!

Ti o ba tilẹ ṣe wipe iba awọn ọmọluwabi ti o wa ni Ilu Oyinbo nikanṣọṣo ni Arẹmọ-oba mọ, ko ni ṣai ti gburo awọn ipata ti o kù ninu Iwe-irohin wọn. Ṣugbọn gẹgẹ bi a ti sọ ni ọsẹ ti o kọja, Gomina tabi awọn Oyinbo abẹ rẹ nikan kọ ni Arẹmọ-oba nbọ wa kí, ẹni pataki ti o fe ri julọ ni iwọ ati emi; ati iba ibiti o ba le de ni ilẹ wa ki o to pada lọ si ile, lati lọ rohin fun Baba rẹ.

Oyinbo ti o pọju nibẹ nikan kọ ni kokoro ti o ba ehin Igbimọ ti Gomina yan yi jẹ, ohun miran ti o ba a jẹ ni wipe, lẹhin ti Gomina ti fi ilana eto ranṣẹ si Ilu Ọba tan nipasẹ bi Arẹmọ-oba yio ti lo akoko rẹ si larin wa, ni o to ṣeṣẹ wa yan Igbimọ, eyiti o jọ l'oju wa wipe, Gomina fi kẹkẹ ṣiwaju ẹṣin.

Boya ibaṣe wipe Gomina ti yan Igbimọ ṣiwaju, a ba ri ẹniti yio gba a ni imọran wipe, Ọyọ ko nṣe ibiti o yẹ ki o ṣe "Durbar" tabi apejọ nla, ninu eyiti o pe awọn Ọba ilẹ wa si lati pade Arẹmọ-ọba nibẹ. Ṣugbọn, nigbati o ṣe wipe ita tabi ọgba *Resident*, (Oyinbo Ọyọ) ni Gomina yio ṣe Durbar tabi Ipade nla na, ti ko si nṣe ninu Agbala Alãfin Ọyọ, o san pupọ. O da wa loju wipe, Oyinbo kan ko le jeun yo tan, ki o sọ wipe, Ọyọ ni olori tabi Olu-ilu ilẹ Yoruba; o si tun da wa loju, ẹwẹ, wipe ko nṣe iru ero bẹ li o wa ni ọkan Gomina, nigbati o fi Durbar tabi Ipade nla na si Ọyọ.

Sibẹsibẹ, gẹgẹ bi Oniwe-irohin, ati gẹgẹ bi ọmọ Yoruba ti awa papa jẹ, ipo wa ni lati sọ fun Gomina wipe, o lodi patapata si ofin ilẹ wa, wipe ki agbalagba lọ si Ipade ni ile ọmọ kekere. Ki a ma tilẹ ṣeṣẹ sọ ti Oni Alayeluwa, Ọba Ile Ife, olori gbogbo wọn, Ọba lẹhin Alake ti Abẹokuta, Ọba lẹhin Oṣemọwe ti Ode Ondo, Ọba lẹhin Ọwa ti Ileṣa, ani Ọba lehin Ọba Yoruba miran, ni Alãfin Ọyọ jẹ. Nitorina, gẹgẹ bi ofin ati iṣẹdalẹ Yoruba, ibiti a ba pe ni ori, a ko nfi tẹ ilẹ!

Ṣugbọn, ọrọ ti o de ilẹ yi dabi a-ṣoro 'di bi iṣu mẹta, o so ọgbọn kọ, o so wère kọ. Imọran ti a si le fun awọn Ọba wa ni wipe, ki nwọn fi ẹjẹ sinu, tu itọ funfun jade, ki nwọn ma si ṣe jẹ ki ohunkohun di wọn l'ọna lati ṣe ẹyẹ, ati lati bu ọlá fun Arẹmọ-ọba, ẹniti ọlá nṣe tirẹ!

Ohun miran ti o tun ba Igbimọ ti Gomina yan jẹ, lẹhin Oyinbo ti o pọ l'apọju ninu rẹ, ati kẹkẹ ti o fi ṣiwaju ẹṣin ni akoko ti o yan a, ni wipe, Enia Dudu pataki ni ilu, ti o yẹ ki o wa ninu rẹ ni ko si nibẹ, ati wipe, pupọ ninu iba awọn Enia Dudu diẹ ti o si wa nibẹ ni Dokita Randle ati awọn abẹyọ rẹ.

Ohunkohun ti o wu ki Gomina le ro ki o to yan wọn bẹ, ati titi yio fi la idi rẹ li ọna ti yio tẹ wa lọrun, ni awa yio fi ma ro ninu ero wa gbangba wipe, bi ko ba jẹ wipe nwọn kó si Gomina l'abẹ ni, ki o to ṣe ohun ti o ṣe ti a nsọ ọrọ rẹ yi, nje, Gomina papa ni l'ọwọ, o di s'ẹru pẹlu; ayaṣebi ko ba mọ orukọ awọn mẹjọ ti Dokita Randle fi ranṣẹ

si Lọya Shyngle wipe on fẹ ki o wa ninu Igbimọ fun Arẹmọ-ọba.

Nigbati edekoyede wa larin ilu ati awọn Dokita Randle nipasẹ iyẹsi ti a o ṣe fun Arẹmọ-ọba, ati nitori ki gbogbo ilu le parapọ ṣe ẹyẹ nla, awọn agbagba l'ọtun-l'osi ṣe aṣaro larin ara wọn, adehun si wa larin Ọlọla Loya Shyngle pẹlu Dokita Randle lojú Ọgbẹni B. C. Vaughan, Ọlọla Kitoyi Ajasa, Ọlọla Eric O. Moore, ati Ọgbẹni G. Debayọ Agbebi, wipe, Ọlọla Loya Shyngle yio mu enia mejila wa ninu ọpọ enia ti o wa lẹhin rẹ, Dokita Randle yio si mu mẹfa wa ninu diẹ kiun tirẹ, gbogbo wọn yio si jumọ papọ ṣe Igbimọ.

Lẹhin ti Lawyer Shyngle fi orukọ enia mejila ranṣẹ tan, ni Dokita Randle ṣẹṣẹ wa kọ iwe pe o ni lati jẹ enia mẹjọ mẹjọ l'ọtun losi, Herbert Macaulay ati Adamu Animashaun ko si gbọdọ wa ninu enia mẹjọ ti Ilu ba yan. Bi Dokita Randle ti ṣe fi kunmọ fọ irẹpọ ti ba wa ni'lu yẹn.

Ṣugbọn ohun ti a fẹ tọka si pataki ni pe lẹhin ti a ba yọ enia dudu mẹfa ti sẹria ipo wọn ninu Igbimọ *Legislative Council* ati *Municipal Council* jẹ ki nwọn wa ninu Enia Dudu mejila pere ti Gomina yan si Igbimọ fun Arẹmọ Ọba, boya ni a le ri ẹnikanṣoṣo ninu awọn mẹfa to ku, ti ki nṣe abẹyọ Dokita Randle.

Orukọ awọn mẹfa to ku ni nwọnyi.

1. Doctor Randle
2. Mr. Peter Thomas
3. Doctor Ọbasa
4. Lawyer A. Alakija
5. Doctor Savage
6. Mr. G D. Agbebi.

Ẹ jẹ ki a yẹ nwọn wo ni ọkọkan lati mọ iba wo ni nwọn da ko Dokita Randle! Randle ni baba ẹgbẹ *People's Union* ti nwọn nṣe ni Ilupesi, ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ na si ni *Doctor* Akinwade Savage nṣe. Orukọ Peter Thomas, orukọ *Dr.* Ọbasa ati orukọ A. Alakija wa ninu awọn orukọ ti Dokita Randle fi si Igbimọ to jẹ alaga fun, Njẹ, a bere, lẹhin awọn mẹfa ti Ipo wọn ninu Igbimọ Ilu ati ti Munisipa gbe de bẹ, talo tun ku ninu awọn Enia Dudu mẹfa ti Gomina yan kun wọn ti ko nṣe abẹyọ Dokita Randle?

Melọ wayi o ni Gomina mu ninu orukọ enia mejila ti Ilu yan? Ko mu ẹnikanṣoṣo ninu wọn, afi awọn ti sẹria Ipo gbe de bẹ! Ọrọ re o, aladugbo; o jọ gate, ko jọ gate, o fi ẹsẹ mejeji tiro. Bẹni Gomina, ati awọn Oyinbo, ati Dokita Randle nikan kọ ni Arẹmọ Ọba nbọ wa ki!!

Ẹlomiran le wipe, ṣe Ilu ni Aṣoju mẹta, Shyngle, Moore ati Jones; ati pe awọn mẹtẹta ni Gomina si yan si Igbimọ fun Arẹmọ Ọba, nitorina iregbe wo la tun nwi? Bẹni nitotọ. Ṣugbọn esi ti a o fi i ni pe ṣe Gomina papa ko ṣai mọ pe awọn mẹtẹta lo nṣoju gbogbo ilu Eko, ko to tun lọ yan *Doctor* Randle, Mr. Peter Thomas, *Dr.* Ọbasa, Mr. A. Alakija, Mr. Agbebi ati *Dr.* Savage, awọn ti a ro pe Gomina ko ṣai mọ pe ninu gbọn,mi-si omi-kotc ni pupọ, ninu wọn pẹlu Ilu wa. Bẹni Ilu ni Gomina nfẹ ki o wa ṣe aṣeyẹ fun Arẹmọ Ọba.

Onifila funfun kan ko si ninu Igbimọ ti Gomina yan. Bişọpu Ṣọṣi Gẹsi, ti Ṣọṣi Aguda ati Afa Ṣọṣi Wesleyan wa nibẹ. Ko si Afa Ṣọṣi alaribọmi *Baptist*, ko si ti Ṣọṣi Ibile *African Church*, ko si ti "Ọlọrun kan" *Unitarian*, ko si aṣoju Musulumi kan nibẹ, bi a tilẹ wipe ko si Lemọmu to gbọ ede Gẹsi daradara to le sọ ni Igbimọ, a ha le fẹ Loya Musulumi ku, to le ṣe oju awọn Imale bi?

Oyinbo Gẹsi onişowo wa nibẹ ṣugbọn ko si Enia Dudu onişowo, bẹni Ṣabu owo Joe (Doherty) ju ti ọpọlọpọ Oyinbo miran lọ. Baba ẹgbẹ awọn akọwe—*Presidents of the clerks' Unions* ko si ninu Igbimo ti Gomina yan, ko si ti awọn oşişẹ *Mechanic's Union*, enia pataki nilu bi Ọgbẹni Herbert Macaulay ko si ni Igbimọ na, David Taylor, Lawyer E. J. Alex Taylor, Thos: Jackson, Adeoye Deniga, "*Scrutator*" ati oniwe irohin miran, *Doctor* Ṣapara ko si nibẹ, bi o sa ti nşe işẹ Ọba ni awọn Oyinbo ti Gomina yan nşe pẹlu, *Doctor* Magnus Macaulay ko si nibẹ, ko si Bagan Benjamin, ko si Alli Balogun ko si Abibu Oki Balogun, *Dr.* Moses Da Rocha, melo ni a o ka ninu enia pataki pataki n'ilu to yẹ ki o wa ninu Igbimọ na ti Gomina ko pe sibẹ, nigbati o mọ pe awọn aşoju Ilu mẹta to wa nibẹ ko tẹ on l'ọrun.

Asiko diẹ kiun lo ku fun Ọlọla Hugh Clifford larin wa, inu wa yio si dun ti o ba jẹ fi asiko diẹ na to ku ṣe ohun ti yio tẹ Ilu lọrun, ti Ilu yio si ma ṣe adara fun-un titi lai. Ẹru Ọba ni mo ba, Eleko. *God save the King.*

## IWE ASỌTẸLẸ TI CAPRICORNUS

Adupẹ pupọ fun iwe asọtẹlẹ ọdun ni ti "*Capricornus*" fi ta wa lọrẹ. *Capricornus* ni na yio jo popọ, ina njo. O ni awọn enia pataki to nile ati ilẹ kitikiti yio ku, I. B. Williams ati Dada Adeshigbin ku. Ọlọrun ko fi ọrun kẹ wọn. O ni ewu ojiji wa, Mọtọ tẹ ọmọ kan pa lori *Bicycle*, o ni onişowo yio jere, ẹniti o ra ibọsẹ onişile kan ni Ṣabu Lever nta a ni şile kan abọ, njẹ *Capricornus* riran, tabi ko riran? Ko bẹ wa ni ipolowo ọja, ṣugbọn a tọrọ gafara lọwọ oniwe irohin wa lati kede rẹ fun Ilu pe şile kọkan ni a nta iwe na, ẹ si le ri i ra ni nṢabu "Eleti Ọfẹ."

## IKU DADA ADESHIGBIN.

*How are the mighty fallen, and the weapons of war perished. Our sympathy goes to the bereaved family.*

Emi ni ti nyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

## *FROM THE EDITOR'S OBSERVATORY.*

### "Moses My Servant is dead!"

The whole community was suddenly plunged into great mourning on Sunday last in the unexpected demise of our respected townsman Mr. Dada Adesigbin of Singer Sewing machine fame: the funeral which took place on the following Monday at Bethel Church at 9 a.m., was attended by quite an overflowing sorrowing crowd which testified in a large measure to the esteem in which the dead philanthropist was held.

We deeply sympathise with Mr. Akin: Adesigbin, Mr. Oke Adesigbin, Mr. J. Layeni the children, and other members of the deceased's family.

### Mr. Ayo Ajala A. Mus. V. C. M (Lond.)

Our friend Mr. Ayo Ajala, A. Mus. V.C.M. (Lond.), of Phillips Medicine Store, is writing a special Dirge to be used in connexion with an Oration we are (D.V.) delivering on the deceased at Ilupesi Hall on Tuesday, the 3rd *proximo*.

### A Schoolmaster's 30 years' faithful services rewarded

Congratulations to our friend, Prince J. B. Ogunjimi Losi of Macaulay Street Lagos, on his being placed on the pension list in the Roman Catholic Missionary Society in this country, on his retirement from the class-room after 30 years' devoted services.

The Arthor-prince has since joined the local firm of Messrs S. Thomas & Co., in their head Office at 1, Williams Street.

### An Induction Service.

The Rev. John F. Ogunko who until recently was Pastor at Christ Church Ebute Meta (U.N.A.) will be inducted as Pastor of Jehovah Shalom U.N.A. by the Rev. Supt. D. A. Hughes tomorrow at 9 a.m.

We bespeak a full house for this pushing cleric

### A Gala Day.

The Jamat Muslims' Victory March took place yesterday from 2 p.m. to 5.30 p.m., amidst much pomp and magnificence.

### Rest in Peace.

Prince Buraimah Adele exchanged time for immortality yesterday.

R. I. P.

ỌPA TI A GBE LE ⱩA TI ẸHIN LOJU.

## ILE AGBE PẸKUN.

Bi o ba nfẹ posi ti o dara fun lilo nigbati akoko ba de, maṣe gbagbe lati lo si ọdọ awọn Ọgbẹni wa wọnyi, nibẹ ni o ti onirũru posi ti a ti ṣe lọṣọ fun lilo., owo diẹ ni a nta wọn.

Ranti maṣe gbagbe ki Ala jẹ ki ọmọ gbẹhin wa o.

Ile Iṣẹ

J. S. BAMGBOSE
ATI J. SOARIES
*Builders and Contractors.*

No. 161, Igbosere Road,
Lagos.

[ *Copyright* ]

## "EKO AKETE" LAW REPORT.

[ Lati ọwọ ATOLUGBOKUN. ]

### SUITS.

Niwaju Ọlọla Frederick Alan Van der Meulen ni ọjọ Tuesday ijo kẹwa oṣu yi ni Kotu Ganran ni ẹjọ larin G. B. Ollivant & Co. Limited ati John Christian trading *as* J. Christian & Co. Lọya Moore agba lowa fun awọn Oyinbo Ollivant Lọya Hagley lowa fun awọn Oyinbo J. Christian & Co.

*Suit No. 231/24.*

*"For an injunction to restrain the defendants their servants and agents from passing off or attempting to pass off or enabling or assisting others to pass off the defendants goods as and for the plaintiffs' goods as per particulars.*

*An order for delivery up on oath of all cotton piece goods or other similar goods bearing the offending words marks and figures or any of them. Damages or an account of profits.*

### "OYINBO ỌTAJA TA ORUKỌ."

Ejọ ti awọn oyinbo G. B. Ollivant & Co. pe nipe fun ida doro ọja ti owa ni ọwọ awọn Oyinbo J. Christian tabi Oyinbo agba, tabi ọwọ iṣẹ ẹnito wun kojẹ ninu ibi iṣẹ awọn Oyinbo yi, ki wọn ma le ko lọ, tabi ko ma yengẹn gẹgẹ bi iwe ẹjọ ti awọn fi si Kotu. Ikeji ni pe fun aṣẹ Kotu lati gba awọn aṣọ wọnyi lọwọ wọn lori ibura tabi eyiti oba ti ẹ fi ara jo aworan "Ẹṣin" "*Horse Trade Mark*" ti awọn nlo, ti oni ọrọ ami, tabi nomba eyi ti o wun ko jẹ. Lehin na awọn fẹ iṣiro ere ti awọn Oyinbo yi ti jẹ ati ẹbun fun janba yi. Loni ijọ kẹwa oṣu February 1925 ni Adajọ ka idajọ rẹ lori ẹjọ yi.

Awọn Oyinbo J. Christian & Coy bere ibi ti ọja ta si gbọn ko bere ori. Awọn oyinbo G. B. Ollivant ni wọn ti nlo aworan "Ẹṣin" yi fun aṣọ wọn ki awọn Oyinbo J. Christian & Coy ki won to la sẹ irufẹ aworan yi. Adajọ la ẹjo yi si orişirişi ọna ti ko yẹ wipe eyi to jọ aworan yi, ko ni lati wa ni ọwọ awọn Oyinbo J. Christian & Coy nitori na on ada awọn Oyinbo G. B. Ollivant & Coy ni are ekini nipe awọn Oyinbo J. Christian & Coy wọn ko gbodọ lo irufẹ ami yi ikeji ni pe gbogbo aṣọ to wa lọwọ wọn, ki wọn ko pada lọ si ọdọ awọn Oyinbo G. B. Ollivant & Coy. Nitorina ki wọn san *(25 Guineas Cost)* Pọun mẹdọgbọn Ṣile mẹdọgbọn owo irin ẹsọ.

### "IRAWE KI DAJỌ ILẸ KO SUN ỌNA."

Irohin kan ni pe Ọgbẹni Ewumi Macarthy ti Lewis Street ni Eko, to lọ si ilu Oyinbo ni oṣu meji ọhun, awọn alaga agbala (*Inner Temple*).

won gba si nu agbo won ni ijọ kọkandilogun oṣu January 1925 fun ati kọ iṣẹ Loya. *(Entered Inner Temple on 19th of January 1925 for purpose of reading law)*. Ewnmi odi ọwọ rẹ o."

Niwaju Ọlọla Frederick Alan Van der Meulen ni ijọ Tuesday ijọ kẹwa oṣu February 1925 ni ẹjọ Matan ati Maroya, *Suit No. 162/24*. Loya Ayo Williams lowa fun Matan, Loya Moore agba lowa fun Maroya

"Gba ran mi ṣe di ẹlẹru Aji ni fẹ ki di ọkọ eni":

*"For the recovery of possession of all that piece of land with the building thereon situated at Itun-nla, Ikorodu, now in possession of the defendant and also for an account of all rents and profits due from the defendant to the plaintiff since 1909 in respect of the same premises."*

Ohun ti Matan pe ẹjọ fun on ni a ko si oke ni ede Oyinbo on ni pe on fẹ gba ile on ti Maroya nlo, to wa ni Itun-nla, igbereko Ikorodu eyi ti Maroya wa lori rẹ ati fun owo to gba lori ile yi ati ere to ri ni bẹ lati ọdun 1909 ti oti nra landa ninu ile yi. Lọya Moore onilakaye enia to wa fun Maroya o ri pe ka fun ni nile gbe ko ledi tẹni, ko fẹ ṣe yẹyẹ pẹlu ara rẹ ninu ẹjọ yi. Sugbon Adajọ ba Maroya sọrọ wipe ko si ọnọ to le fi sọ pe Matan ko le le ẹ jade ni asiko to ba wun. Maroya ni on ma sọ ti on iyẹn nipe Baba on ati Baba Matan ikan ni wọn jẹ wọn jẹ ọrẹ papa, nigbati Baba Matan ku Baba on lo sin, ati kekere ni on ti wa ni ọdọ Matan, on lo si kọ ile ti Matan fẹ gba lọwọ on, sugbọn a mọ wipe on kọ lon, ati pe on ti nlo ilẹ na ọjọ pẹ nisinsinyi, Adajọ ni itan lo npa, aye ko si fun yen, sugbọn on aba ẹ bẹ lọya Matan ko fun o ni aye die, eyẹn ni pe ko fi wa ibo miran, ohun Adajọ da ẹ lebi, ko kuro ni ile na ni ipari oṣu March 1925. Ki Matan si gba ilẹ rẹ. Adajọ ni ki Maroya san ( *30 guineas*) ọgbọn pọun ọgbọn ṣile owo irin ẹsẹ fun Matan.

---


# Dada Adeshigbin

THE MAN AND HIS MISSION.

## An Oration

On the above subject will ( D. V. ) be delivered to the general public, with particular reference to the members of the African Church Organisations

by

**PROF. DEDIGA**

Editor :—*Eko Akete*, Lecturer, and Author.

At Ilupesi Hall, Enu-Owa on Tuesday the 3rd *Proximo.*

Further particulars will be announced later.

*Eko Akete Offices,*
22, 24, Williams Street,
Lagos.


NATIONAL CONGRESS OF BRITISH WEST AFRICA.

Notice is hereby given that a general meeting of Local Branch of the National Congress of British West Africa will take place at the Committee Room of the Glover Memorial Hall Lagos on Monday the 16th day of February 1925, at 5. 30 p.m. precisely.

Posters will, in due course, issue to remind the public.

Dated at Lagos the 31st day of January, 1925.

A. L. JOHNSON,


**The West African Soap Co. Limited**

**APAPA, NIGERIA**

*Manufacturers of*

**NEPTUNE**

PALE SOAP

**BUGLE**

PALE SOAP

**MAGNET**

CARBOLIC SOAP

will send Price Lists and terms to merchants upon application to

**P.O. Box 522**

**Lagos**

**Nigeria**

F 393

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yio ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)
Masses Isin Arọ.
6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30
(EVENING.)
(Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30
ST. MICHAEL'S ) Lafiaji.)
MORNING. 7—8 8.30—9.30
EVENING. 5.45—6.30

ANGLICAN

Time. Preacher.
9 a.m. Christ Church, The Vicar
6.30 p.m. do. do.
9 a.m. St. Paul's (Breadfruit) Rev. C. A. Ṣowunmi
6.30 p.m. do. Rev. J. O. Lucas
9 a.m. St. John's (Aroloya) Bishop I. Oluwọle
6.30 p.m. do. Rev. H. V. E. Jhonson
9 a.m. & 630 p.m. St. Peter's (Alapako)
Rev. S. V. Latunde
9 a.m. & 6.30 p.m. Holy Trinity (Ebute-Ero)
Rev S. J. Gansallo
9 a.m. St. David's (Jordan) Rev. J. H. Ogunko
6 30 p.m. do. do.

WESLEYAN

10.30 a.m. Tinubu Rev. J. Allen Angus
7 p.m. do. Rev. A. N. Cole
10.30 a.m. Ereko Rev L. R. Potts Johnson
7 p.m. do. Rev S. A. Pearse
10.30 a.m. Olowogbowo Rev. E. E. Williams
7 p.m. do. Bro. S. G. Johnson
10.30 a.m. Ọbun Eko Rev. S. A. Pearce
7 p.m. do Bro. E. A. Davies

AFRICAN (COMMUNION)

9 a.m. Jehovah Shalom Rev. Supt. D. A. Hughes
7 p.m. do. Rev. J. F. Ogunko
9 a.m. Christ Church (Ebute Mẹta)
Bro. W. K. Fafunwa
7 p.m. do Bro. Ọlaboye Laleyẹ
9 a.m. Bethel Rev. I. O. Oyekunle
6.30 p.m. do. Rev. F. David Ṣodẹinde
9 a.m. Zion Rev. N. J. D. Ṣomuji
6.30 p.m. do. do.
9 a.m Salem Church (Ebute Mẹta)
6 30 p.m. do.
9 a.m. Bethlehem Church (Ebute Mẹta)
do.
10 a.m. African Methodist Bro. J. A. Osodi
do Rev. I. O. Oyekunle

FIRST BAPTIST CHURCH

10.30 a.m.
6.30 p.m. Rev. J. R. Williams.

(EBENEZER BAPTIST)

9 a.m. Rev. E. C. Alabi
6.30 p.m. do.
9 a.m. Ararọmi (Baptist)
6 p.m.

BROTHERHOOD. CONGREGATION

7.30 a.m. Ilupesi Resp'ble Bro. A. Ajọṣẹ-Adeogun
7 p.m. Pastor A. Ibaru

St. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Rev. B. A. Wifunkẹ.

AHMADIA (ISLAM.)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajoṣe
(Central Mosque, Arọloya Street.)

ZION CONGREGATIONAL

9 a.m. Kakawa St. Locum Tenens.
7 p.m. do. do.

SALVATION ARMY

10 a.m. Glover Memorial Hall
Capt. A. A. da Costa
7 p.m. do.

CHURCH OF GOD

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square
Wm. C. T. Terrell.

---

ỌMỌ OKUYANMUYANMU.

Gbogbo awọn ọmọ Oloye ni Eko ati agbegbe rẹ lo npejọ si Ilupesi Ẹnu-ọwa, ni ọ'jọ Satide Satide, lati ma gbero ohun ti yio jasi idagbasoke ilu wọn.

Ẹnikẹji, o ti fi orukọ silẹ nibẹ bẹ? Owe kọ ni a fi nwọ ẹgbẹ yi, ọla ni, o ni ipo ninu ẹgbẹ yi, niwọn ti o ba ti jẹ ọkan ninu ọmọ oye wọnyi.

1. Akarigberi
2. Ọgalade
3. Idejọ
4. Ogboni Olorogun

"Ire ilu rẹ ni ki o jẹ ẹdun ero rẹ"

JAMES ỌLADIPỌ HOTONU
DAVID AJE OGUNLANA
*Awọn Akọwe Ẹgbẹ.*